# Wúnrẹ̀n *ti* Inú Àpólà Orúkọ Oníbàátan Kì í Ṣe Ọ̀rọ̀-Orúkọ

**Ọládiípọ̀ Ajíbóyè**
*Depatment of Linguistics, African and Asian Studies*
*University of Lagos*
*oladiipo@yahoo.com*

## Àṣamọ̀

Èrò méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ló wà lórí wụ́nrẹ̀n **ti** inú Àpólà orúkọ Oníbàátan. Ọ̀kan ni pé ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò orúkọ ni. Èkejì ni pé wúnrẹ̀n aṣegírámà tí ó jẹ́ atọ́ka ìbátan ni **ti**. Iṣẹ́ tiwa yìí ṣe àyẹ̀wò fínnífínní àwọn ẹ̀rí tuntun tó ṣègbè lẹ́yìn èrò pé ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí arọ́pò-orúkọ ni, ó sì tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pẹ̀lú àlàyé tó ṣeé gbáralé pé jíjọ ló kúkú lè jọ lójú àwọn kan, wúnrẹ̀n náà kò ní ìrísí tàbí ìfọ́nká ọ̀rọ̀-orúkọ, bẹ́ẹ̀ ni kò lè ṣe iṣẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ rárá bí kò ṣe wúnrẹ̀n tó dúró gẹ́gẹ́ bi orí (atọ́ka ìní) nínú Àpólà-orúkọ Oníbàátan kíkún tàbí agérí (ìyẹn àpólà Oníbàátan (APIT) tí àpólà ọ̀rọ̀-orúkọ ìní inú rẹ̀ ti pòórá). Iṣẹ́ yìí gùn lé Tíọ́rì Onípele (X-bar Theory) lábẹ́ tíọ́rì Onídàrọ níbi tí ohunkóhun tó bá ti jẹ́ orí gbọ́dọ̀ yọ sókè di àpólà, tí irú orí bẹ́ẹ̀ sì lè ní amúpé áti asọdọ̀tọ̀.

## Ìfáárà

Ọjọ́ pẹ́ tí Ọ̀jọ̀gbọ́n-fèyìntì Awobuluyi ti ń fọnrére pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni ***ti*** tí a máa ń ṣe alábàápàdé rẹ̀ nínú Àpólà orúkọ Oníbàátan (Awobuluyi 2004, 2008, 2013). Ọ̀kan lára àpẹẹrẹ tí Awobuluyi sábà máa ń tọ́ka sí láti fi ṣègbè lẹ́yìn èrò wọn náà ni ó wà ní (1).

(1) a. ti èmi

b. ti òtítọ́ (Awobuluyi 2013: 23)

Ìbéèrè tí ó ń fẹ́ ìdáhùn ni pé ṣé bí ọ̀rọ̀ ti rí gẹ́lẹ́ nìyí? Lójú ti aṣèwádìí yìí, "Rárá o", ni ìdáhùn máa jẹ́. Ète àtifidí ìdáhùn náà múlẹ̀ ni a ó pa nínú iṣẹ́ yìí. Bí a ó ṣe mú iṣẹ́ náà ṣe ni kí a kọ́kọ́ fi èrò Awobuluyi hàn pẹ̀lú àwọn àlàyé àti apẹẹrẹ wọn ní ìsọ̀rí (2), kí a sì sọ ìdí tí a kò fi gbà pé ***ti***[1] jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò orúkọ bí kì í ṣe wúnrẹ̀n aṣegírámà tó ń ṣiṣẹ́ atọ́ka ìní. A ó ṣe àlàyé pẹ̀lú àwọn àpẹẹrẹ tí ó ṣeé gbára lé ní ìsọ̀rí (3) láti ṣe àtìlẹ́yìn èrò tiwa. Ní ìsọ̀rí (4) ni a ó ti ṣe àfihàn bí tíọ̀rì Onípele ti máa ṣe àlàyé ìhun tí a dábàá. Bí ọkọ̀ bá ròkun, rọ̀ṣà; ó di dandan kó fàbọ̀ sí èbúté. Ìsọ̀rí (5) ni a ó ti gúnlẹ̀ iṣẹ́ wa.

## Èrò tó ṣègbè lẹ́yìn *ti* gẹ́gẹ́ bí Ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò-orúkọ

Èrò méji tó fara pẹ́ ara wọn ni Awobuluyi ní nípa ***ti***. Èkínní ni wí pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni. Èkejì ni pé ó tún lè jẹ́ arọ́pò orúkọ. A ó wo ọ̀kọ̀ọ̀kan èrò méjì yìí ní síṣẹ̀ntẹ̀lé ní ìsọ̀rí 2.1 àti 2.2.

## 2.1 Èrò tó ṣègbè lẹ́yìn *ti* gẹ́gẹ́ bí Ọ̀rọ̀-orúkọ

Ẹ̀rí àkọ́kọ́ tí Awobuluyi tọ́ká sí láti ṣègbè lẹ́yìn pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni ***ti*** ni pé ó lè gba àfibọ̀ fáwẹ̀lì ***i***. Èyí jẹ́ ọ̀kan lára àbùdá àdáni tí Awobuluyi gbà pé ọ̀rọ̀-orúkọ ní. Ẹ wo ohun tí Awobuluyi sọ ní pàtó:

---

[1] Àwọn onímọ̀ bí Ọ̀jọ̀gbọ́n-fẹ̀yìntì-gbẹ̀yẹ Ayọ Bám̄gbóṣe àti Ọ̀jọ̀gbọ́n-fẹ̀yìntì Kọ́lá Owólabíti sọ ohun tí ó fara pẹ́ èrò tiwa lọ́jọ́ tó ti pẹ́. Ohun tí wọ́n pe **ti** ni atọ́ka ìtẹ̀numọ́. Ohun tí èrò Bám̄gbóṣe àti Owólabí fi jọ ti aṣèwádìí yìí ni pé wọn kò pè é ní ọ̀rọ̀-orúkọ. Wọ́n kò sọ ju pé ọ̀rọ̀ ìtẹ̀numọ́ ni wúnrẹ̀n náà nítorí pé ní àsìkò tí wọ́n ṣe iṣẹ́ tiwọn, kò tí ì sí èrò kan tí a mọ̀ tó tako pé iṣẹ́ ìtẹ̀ǹumọ́ ni **ti** ń ṣe; bẹ́ẹ̀ ni, wọn kò gbé àlàyé wọn ka orí tíọ̀rì kan pàtó.

> …bí ***Tútù*** bá jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ tìtorí bí ó ṣe fàyè gba fáwẹ̀lì ***i*** aláfibọ̀, dandan ni kí ***ti*** náà jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ, nítorí pé òun náà máa ń fàyè gba fáwẹ̀lì ***i*** aláfibọ̀ bí ó ti ṣe nínú àpẹẹrẹ òkè yìí… (Awouluyi 2013: 20)

Àpẹẹrẹ tí Awobuluyi ń tọ́ka sí ni ó wà ní (2).

| (2) | **Kíkọ** | **Sísọ** |
|---|---|---|
| | ìwé ti Bọ́lá | ìwé **eti** Bọ́lá |

(Awouluyi 2013: 20)

Ohun tí ó máa wá jẹ́ ìhun àmúwọlé fún un ni **i**+**ti** tí yóò di **iti**. Lẹ́yìn èyí ni òfin àrànmọ́ tó ṣọ ọ́ di **eti** nínú àpẹẹrẹ (2).

Ẹ̀rí kejì tí ó mú kí Awobuluyi gbà pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni ***ti*** ni ti ẹ̀yán bí ***rẹ̀*** tí wọ́n lérò pé ó lè gbà bí ó ti hàn ní (3b).

| (3) | | **Kíkọ** | **Sísọ** |
|---|---|---|---|
| | a. | ìwa rẹ̀ | ìwa a rẹ̀ |
| | b. | tirẹ̀ | tirẹ̀ (← ti **i**rẹ̀) |

(Awobuluyi 2013: 21)

Bí èrò yìí bá wọlé, a jẹ́ pé gbogbo arọ́pọ̀ orúkọ bí **wa**, **yín**, **wọn** abbl àti ọ̀rọ̀-orúkọ bí **Adé Kúnlé**, **Tòkunbọ̀** abbl ni yóò jẹ́ ẹ̀yán. Ẹ̀rí kẹ́ta ni:

> …pé ***ti*** (pẹ̀lú ẹ̀yán rẹ̀) ṣe amúpé fún ***ní***, tí ó jọ pé gbogbo èèyàn kà sí atọ́kùn. Bí ***ti*** ṣe lè jẹ́ amúpé fún ní ẹ̀rí kẹ́ta tí ó fi hàn dájú pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni; kì í ṣe 'atọ́kùn' tàbí 'atọ́ka ìtẹnumọ́' tí àwọn kan kà á sí.
> (Awobuluyi 2013: 23-24)

Àpẹẹrẹ tí ó tún gbe èrò yìí lẹ́yìn ni ó wà ni (4) ìsàlẹ̀ yìí.

(4) a. Èmi ò níí lọ [ní] tèmi (← **ti** èmi)

b. Ọ̀rẹ́ mi [ní] tòótọ́ (← **ti** òtítọ́)

(Awobuluyi 2013: 23)

Ẹ̀rí kẹ́rin ni wí pé ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ tí ó bá lè ṣiṣẹ́ olùwà tàbí àbọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ. Níwọ̀n bí ***ti*** ti lè ṣiṣẹ́ àbọ̀ bí ó ti hàn nínú àpẹẹrẹ (5), nítorí náà, èyí fi hàn wí pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni ***ti***.

(5) …Mi ò gba **ti** sisí náà.

(Awobuluyi 2013: 24)

## 2.2 Èrò tó ṣègbè lẹ́yìn *ti* gẹ́gẹ́ bí Arọ́pò-orúkọ

Ohun tí Awóbùlúyì fi kásẹ̀ ọ̀rọ̀ wọn ni pé arọ́pò-orúkọ ìní ni ***ti*** tí a ń sọ̀rọ̀ bá. Èro Awobuluyi ni wí pé:

> Ẹyọ ọ̀rọ̀ kan ṣoṣo ni a tíì kíyèsí tí ó máa ń dúró fún ohun ìní tàbí ohun tí ó níí ṣe pẹ̀lú ẹni tàbí ohunkànkan nínú èdè Yorùbá. Ọ̀rọ̀ náà ni ***ti***.
> (Awobuluyi 2013: 35)

Àpẹẹrẹ tó tún ṣe àtìlẹ́yìn ohun tí Awobuluyi sọ ni a fi hàn ní (6) àti (7).

(6) a. O ti rí mọ́tò Olú?

b. Mo ti rí i; ṣùgbọ́n mi ò tíì rí **ti Báyọ̀**

(Awobuluyi 2013: 35)

(7) a. ajá **ti** Túndé (**tì** → **ti** jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe)

b. ajá **ati** iTúndé (**ti** jẹ́ arọ́pò-orúkọ (aṣèyán-oníbààtan) (Awobuluyi 2013: 60)

Gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àpẹẹrẹ (7), ní èrò ti Awobuluyi, arọ́pò-orúkọ tí ó jẹ́ èyán oníbààtan ni ***ti***.

Ní ìsọ̀rí kẹ́ta ni aṣewádìí yóò ti fi èrò tirẹ̀ hàn lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan èrò Awobuluyi wọ̀nyí pẹ̀lú ète àtifidí rẹ̀ múlẹ̀ ní ìlànà tíọ̀rì onípele pé wúnrẹ̀n aṣegírámà tí ó dúró gẹ́gẹ́ bí orí fún àpóla oníbààtan ni ***ti,*** kì í ṣe ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí arọ́pò orúkọ rárá***; ti*** yìí gan-an ni ó sì ń ṣiṣẹ́ atọ́ka ìní tí ó so apòlá ohun tí a ni àti olóhun pọ̀.

## Èrò tó ṣègbè lẹ́yìn *ti* gẹ́gẹ́ bí Atọ́ka Ìní

Lẹ́yìn tí a ti ṣe àfihàn àwọn ohun tó dúró bí ẹ̀rí fún Awobuluyi láti ka ti sí ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò-orúkọ pẹ̀lú àwọn àpẹẹrẹ láti ti ẹ̀rí kọ̀ọ̀kan lẹ́yìn, ó tọ́, ó sì yẹ kí aṣèwádìí yìí gbé àbá àti àlàyé tó gbà pé atọ́ka ìní ni **ti** kalẹ̀ pẹ̀lú àlàyé àti àpẹẹrẹ tó dúró gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rí fún èrò náà. Ṣùgbọ́n kí a tó ṣe ìyẹn, ó tọ́, ó sì yẹ, ká gbóríyìn fún àwọn aṣíwájú tí wọn ti rin ọ̀nà tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ ń rìn lẹ́yìn wọn nípa ti ipò wúnrẹ̀n yìí.[2] Bámgbóṣé (1966: 108-109, 1967:20, 1990:120-121) ti kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ ṣókí ṣókí nípa **ti**. Ọ̀rọ̀ Bám̄gbóṣe (1990) ló wà nísàlẹ̀.

> Oríṣi ẹ̀hun oníbààtan kejì ni alátẹnumọ́. Àbúdá ẹ̀hun yìí ni ẹ̀rún oníbààtan **ti** tí ó máa ń wà

[2] Lára àwọn Òjọ̀gbọ́n náà ni Bám̄gbóṣé àti Owólabí.

láàárín orí àti ẹ̀yán… Yàtọ̀ sí ìtumọ̀ ìtẹnumọ́, ìtumọ̀ ìní ni ẹ̀hun yìí sáábà máa ń ní…
(Báḿgbóṣé 1990: 120)

Owólabí (1976) náà kò gbẹ́yìn láti ṣe ọ̀fintótó lórí wụ́nrẹ̀n yìí. Ní pàtó, Báḿgbóṣé àti Owólabí nínú iṣẹ́ wọn tọ́ka sí **ti** gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rún oníbààtan. Èyí wà ní ìbamu pẹ̀lú èrò aṣèwádìí yìí. Nítorí náà, a kò ní àríwísí kan danindanin lórí iṣẹ́ wọn nítorí kìkì ohun tó jẹ aṣèwádìí yìí lógún jù lọ ni ohun tó rọ̀ mọ́ àlàyé lórí **ti**. Bí ọ̀rọ̀ tilẹ̀ rí báyìí, ohun méjì wà tí mo fẹ́ mẹ́nubà nínú iṣẹ́ Báḿgbóṣé. Èkínní ni èrò wọn pé ẹ̀yán ni ó máa ń tẹ̀lé wúnrẹ̀n **ti**. Gẹ́gẹ́ bí a ó ti fi hàn láti àkókò yìí lọ, àpólà orúkọ olóhun ni a gbà pé ó tẹ̀lé wúnrẹ̀n yìí. Ohun keji ni iṣẹ́ tí **ti** ń ṣe nínú àpólà oníbààtan. Òtítọ́ ni pé ìyàtọ̀ ìtẹnumọ́ wà nínú **ilé ọba** àti **ilé e ti ọbạ** gẹ́gẹ́ bí Báḿgbóṣé àti Owólabí ti gbà ṣùgbọ́n yàtọ̀ sí pé **ti** ń ṣe ìtẹnumọ́, ó tún máa ń ṣe iṣẹ́ mìíràn gẹ́gẹ́ bí a ti fi hàn nísàlẹ̀. Ohun kan tó ṣe pàtàkì sí wa nínú iṣẹ́ Owolabi ni pé ó fi hàn dájú gbangba pé àpẹẹrẹ bi **ti Bọ́lá** jẹ́ àgékù **àpóla oníbààtan alátẹnumọ́** (Owolabi 1976: 136tt).[3] Ẹ jẹ́ kí a wá padà sí ẹsẹ tí a ń bá bọ̀.

Ẹ̀rí àkọ́kọ́ tí Awobuluyi tọ́ká sí láti ṣègbè lẹ́yín pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni ***ti*** ní ti pé ó lè gba àfibọ̀ fáwẹ̀lì ***i*** kò dà bí ẹni pé ó lè fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni **ti**. Lọ́nà kìn-ín-ní, èyí nìkan ni irúfẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó máa jẹ́ sílébù kan péré nínú èdè Yorùbá tí a ó ṣe

[3] Ìyẹn ni pé kò pe **ti** ní ọ̀rọ̀-orúkọ. Níwọ̀n ìgbà tí iṣẹ́ aṣèwádìí yìí kì í ti í ṣe àtàkò iṣẹ́ Owólabí, a kò ní sọ jù báyìí lọ. Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé, wo Owólabí (1976).

àfibọ̀ fáwẹ̀lì ***i***. Gbogbo àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tó kù gẹ́gẹ́ bí **Tútù**, **Bọ̀lá**, **Dékọ̀lá,** abbl. ni wọ́n máa ń ní sílébù méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí fẹ́ẹ̀ mú kí ó rúni lójú bí **ti** ṣe máa dá yàtọ̀ sí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tó kù. Kì í ṣe ìṣòro yìí nìkan ni ọ̀rọ̀ fífi fáwẹ̀lì àfibọ̀ pe ọ̀rọ̀ kan ní ọ̀rọ̀-orúkọ fà lọ́wọ́ o. Ẹ ṣe àkíyèsí pé àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ bíi **Bọ̀lá**, **Dékọ̀lá, Kúnlé, Délé** ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú fáwẹ̀lì tẹ́lẹ̀ kó tó di pé a gé sílébù kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ kúrò lára wọn, èyí tó wá mú kí wọ́n bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú kọ́ńsónáǹtì báyìí. Bí àpẹẹrẹ, **Adékọ̀lá** ló di **Dékọ̀lá** nípa yíyọ fáwẹ̀lì **a** kúrò. **Kúnlé** lè jẹ́ **Adé-kúnlé**, **Ògún-kúnle**, **Ọlá-kúnlé**, **Ọ̀jẹ́-kúnlé,** abbl. tí a gé sílébù méjì àkọ́kọ́ rẹ̀ kúrò. Nítorí náà, ọ̀rọ̀ pé fáwẹ̀lì **i** tó wà níbẹ̀rẹ̀ àwọn ọ̀rọ-orúkọ yẹn wà níbẹ̀ láti mú kí ọ̀rọ̀-orúkọ wọ̀nyẹn wà ní ìbamu pẹ̀lú òfin ìhun ọ̀rọ̀-orúkọ níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ kò wọlé rárá. Kò wọlé, nítorí ìfòfin èdè ṣòfò ni yóò jẹ́ kí èdè kan pa fáwẹ̀li kan jẹ kí ó tún ṣe àfibọ̀ fáwẹ̀lì mìíràn kó tó pe ọ̀rọ̀ náà jáde lẹ́nu nítorí pé fáwẹ̀lì gbọ́dọ̀ bẹ̀rẹ̀ irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ó ti fi hàn nísàlẹ̀, fáwẹ̀lì yẹ̀n dá wà gẹ́gẹ́ bí mọ́fíìmù tó ń ṣe iṣẹ́ atọ́ka ẹ̀yán ni, kò papọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ rárá.

Lórí ìṣòro ìhun yìí kan náà, kìkì ọ̀rọ̀-ìṣe ni ó ní ìhun tí **ti** ní tí a lè sọ di orúkọ; ìyẹn àtòpọ̀ kọ́ńsónáǹtì àti fáwẹ̀lì (KF) tí a lè ta mọ́fíìmù àfòmọ́ pọ̀ nínú ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ láti fún wa ní ọ̀rọ̀-orúkọ Yorùbá.[4]

[4] Àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn tí wọ́n tún ní irú ìhun yìí ni ọ̀rọ̀-atọ́kùn, atọ́ka amúpé, ìyísódì abbl., kò sì sí èyíkéyìí wọn tó lè gba àfòmọ́ tó lè sọ wọ́n di ọ̀rọ̀-orúkọ.

Yàtọ̀ sí ìyẹn, tí **ti** bá jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí arọ́pò-orúkọ, tó ń gba ẹ̀yán bí **Bọ́lá**, ó yẹ kí ó lè dá dúró láìgba ẹ̀yán. Ìyẹn ni wí pé, ó yẹ kí a lè rí **ìwé iti → ìwé eti**. Ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀. Ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ nítorí ohun tí Awóbùlúyì pe wúnrẹ̀n yìí kọ́ ni ó ń jẹ́. Ìdí nìyí tí ìpèdè ìsàlẹ̀ ní (8) kò fi nítumọ̀.

(8) a. *__Iti__ ni ìyẹn
b. *Ìwé **iti** ni ìyẹn

Bí ***ti*** bá jẹ́ arọ́pò-orúkọ gẹ́gẹ́ bí Awobuluyi ti sọ, ó yẹ kí ó lè dúró ní ọ̀gangan ibi tí àwọn arọ́pò-orúkọ tókù lè dúró ní (9).

(9) a. Ìwé e **rẹ̀** dà?
b. Ìwé e **rẹ̀** ni ìyẹn
d. *Ìwé e **ti** ni ìyẹn
(f.w. Ajiboye 2011)

Àìlèdúró ní ọ̀gangan ibi tí àwọn arọ́pò orúkọ tó kù lè dúró ní àpẹẹrẹ òkè gba ìfura. Ẹ̀wẹ, kò sí ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí arọ́pò orúkọ tí ó ń hùwà àfòmọ́ bí **ti** nínú èdè Yorùbá ní ti pé kò lè dá dúró bí ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí arọ́pò-orúkọ. Ní èrò tiwa gẹ́gẹ́ bí a ti máa fi hàn ní ìsàlẹ̀, àìnítumọ̀ àti àìbétímu ìpèdè (8) àti (9d) kò ṣẹ̀yìn pé wúnrẹ̀n aṣegíramà tí ó jẹ́ orí àpólà tó gbọ́dọ̀ gba àbọ̀ ni ***ti***; a kò sì lè sọ ọ́ di ọ̀rọ̀-orúkọ àpàpàǹdodo.

Síwáju sí i, lórí ọ̀rọ̀ pé arọ́pò-orúkọ kọ́ ni **ti**, ẹ tún wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

(10) a. O ti rí mọ́tò Olú?

b. Mo ti rí i; ṣùgbọ́n n ko tíì rí **ti** Báyọ̀.

(Awobuluyi 2013:35)

Èrò Awobuluyi ni pé **ti** ni ó dúró fún mọ́tò ni (10b). Àmọ́, kò dájú pé bí ọ̀rọ̀ ṣe rí nìyẹn. Bí a bá ṣe àfihàn ìhun ìpìlẹ̀ àpólà yẹn, ohun tí ìhun náà máa jẹ́ ni ó wà ní (11).

(11) a. O ti rí **mọ́tò ti Olú**?

b. Mo ti rí i; ṣùgbọ́n n ko tíì rí **mọ́tò ti Báyọ̀**.

(Awobuluyi 2013:35)

Ǹjẹ́ bá wo ni àpólà orúkọ ìní, **mọ́tò** ṣe pòórá ní (10b)? Àlàyé rẹ̀ kò rújú rárá. Òfin ayẹ̀dà Àpólà orúkọ (Equi-NP deletion Baker, 1978) ni ó yọ àpólà ìní (10b) tí ó jẹ́ ọ̀kanùn pẹ̀lú ti (10a) kúrò. Nítorí náà, kì í ṣe **mọ́tò** ni **ti** dúró fún ní (10b) rárá. Èdè Yorùbá nìkan kọ́ ni irú ohun tí a ń sọ̀rọ̀ bá yìí ti ń wáyé o. Bí àpẹẹrẹ, Gẹ̀ẹ́sì náà ní irú rẹ̀.

(12) a. Have you seen **John's car**?
Ṣé o ti rí **ọkọ̀ ọ Jọ̀ọ́nú**

b. Yes, I have seen it; but I have not seen **Paul's car**.
Bẹ́ẹ̀ ni, mo ti rí i; ṣùgbọ́n n kò tí ì rí **ọkọ̀ o ti Pọ́ọ̀lù**

d. Yes, I have seen it; but I have not seen **Paul's**.
Bẹ́ẹ̀ ni, mo ti rí i; ṣùgbọ́n n kò tí ì rí **ti Pọ́ọ̀lù**

Níwọ̀n bí a kò ti lè sọ pé **'s** ni ó dípò **car** ní àpẹẹrẹ (12), nítorí atọ́ka ìní níí ṣe, bẹ́ẹ̀ náà ni a kò lè sọ pé **ti** ló dúró fún àpólà ìní. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pe Ọ̀jọ̀gbọ́n Awobuluyi kì í sáábà fẹ́ẹ́ kí a ṣe àmúlò àfijọ láti inú èdè mìíràn, nítorí èrò Awobuluyi ni pé èdè kọ̀ọ̀kan ló dá wà tó sì ní àbùdá tirẹ̀, tí kò sì yẹ kí a ṣẹ̀ṣẹ̀ máa nàgà wo ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lédè mìíràn ṣe àlàyé ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lédẽ̀ Yorùbá; síbẹ̀, gẹ́gẹ́ ṣe gẹ́gẹ́ ni ohun tí ó wà ní Gẹ̀ẹ́sì àti Yorùbá lórí ohun tí a ń sọ̀rọ̀ bá. Ní ìkádìí, a lè fi ògún rẹ̀ gbárí pẹ̀lú àlàyé àti àpẹẹrẹ tí a ti gbé kalẹ̀ pé **ti** kì í ṣe àdàmọ̀dì arọ́pò orúkọ bí kò ṣe atọ́ka ìní inú àpólà oníbààtan.

Ẹ̀wẹ̀ tó bá jẹ́ pé ṣe ni ***ti*** ń rọ́pò ọ̀rọ̀-orúkọ ìní, kí ló fà á tí àwọn méjèèjì ṣe lè jùmọ̀ rìn papọ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn ní (10a)?

Ẹ̀rí kejì tí ó mú kí Awobuluyi gbà pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni ***ti*** ni ti ẹ̀yán bí ***rẹ̀*** tí wọ́n lérò pé ó lè gbà.

(13) a. ti rẹ̀
b. ti wa

Tí ó bá jẹ́ pé arọ́pò orúkọ ni ***ti***, ìbéèrè tó ń fẹ́ ìdáhùn ni pé bá wo ni ó ṣe tún lè gba ẹ̀yán. Ìyẹn nìkan kọ́, tí ó bá sì jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ ni ***ti***, kí ló fà á tí kò fi lè gba fáwẹ̀lì àfibọ̀ níbẹ̀rẹ̀? Àlàyé tó gùn lé pé kìkì sàkáni kan ni ó ti lè jẹ yọ pẹ̀lú fáwẹ̀li ***i***, kò ṣẹ́é gbáralé. Ṣùgbọ́n, tí a bá wo èrò ti wa tó sọ pe wúnrẹ̀n aṣegírámà tó ń ṣiṣẹ́ atọ́ka ìní ni **ti**, o máa ṣeé ṣàlàyé pé inú àpólà-orúkọ oníbààtan akùdé (aláìní àpólà ìní) ni ó ti lè jẹyọ ní àìní fáwẹ̀li ***i*** níbẹ̀rẹ̀.

Ẹ̀rí Awobuluyi kẹ́ta ni pé ***ti*** (pẹ̀lú ẹ̀yán rẹ̀) lè ṣe amúpé fún ***ní***, gẹ́gẹ́ bí ti àpẹẹrẹ (4) lókè. Àmọ́ sá, tí a bá fara balẹ̀ wò ó dáradára, a ó ri pé àwọn ìsọ bí **ní tèmi (ní ti èmi)** kì í ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àpólà onítbàátan. Òye ohun tí a ń sọ níbí máa hàn nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

(14) Ọ̀rúnmìlà ní:

Bó ba ṣe **níṣe tèmi** ni (**ní ìṣe ti èmi)**[5]
Bí ò ba ṣe **níṣe tèmi** ni
Àsọdúnmọ́dún lawo àsọdúnmọ́dún…
(Sunny Ade 1975)

Àpẹẹrẹ (11) ti fi hàn kedere pé kì í ṣe **ti** (pẹ̀lú ẹ̀yán rẹ̀) ni ó ṣe amúpé fún **ní**'. Kò sí ohun tí a lè ka apẹẹrẹ (4) sí ju pé abirùn àpólà oníbàátan níí ṣe. Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àpólà oníbàátan yẹn ni **ìṣe ti èmi**. Gbogbo àpólà yẹn ni ó ń ṣe amúpé fún **ní**.

Ẹ̀rí kẹ́rin ni wí pé ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ tí ó bá lè ṣiṣẹ́ olùwà tàbí àbọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ gẹ́gẹ́ bi ó ti hàn ní àpẹẹrẹ (5) ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí ti àwọn àlàyé ìṣáájú **ti sisí náà** kì í ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àpólà oníbàátan. Ẹ wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

(15) a. **Àbá a ti sisí náà** dára

b. Mo gba **àbá a ti sisí náà**

---

[5] Láméìtọ́ kan tí a kò mọ̀ béèrè ohun tí mo rí sọ nípa ìhun wọ̀nyí:

(i) **Ti tèmi** ni — It's mine'
(ii) Ní **ti tèmi** — 'As for me'
(iii) Kí ni **ti tèmi** — 'What's my business (in that)'

níbi tí **ti** méjì ti jẹyọ.

Lójú tèmi, àsìsọ èdè ni mo máa ka àwọn ìsọ yen si. Àsìsọ ni wọ́n tàbí ká sọ pé èdè ọmọdé. Ìdí ni pé tí a bá yọ òkan nínú ti méjì yẹn kúró kò fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀. Fi **<u>ti tèmi ni</u>** wé **<u>tèmi ni</u>**. Èmi kò rí ohun tó yàtọ̀ nínú ìtumọ̀ méjèèji o.

d. **Ìwà a ti sisí náà** wù mí

e. N kò gba **ọ̀rọ̀ ọ ti sisí náà** rárá o

Kí wá ni ìhun àpólà tí **ti** ti máa ń jẹyọ nínú èdè Yorùbá ní ìlànà tíọ̀rì òde òní? Ẹ jẹ́ ká lọ sí ìsọ̀rí kẹ́rin.

## Ìtúpalẹ̀ Ìhun Àpólà Oníbàátan ní Ìlànà Tíọ̀rì Onípele

Tíọ̀rì Onípele tí Chomsky (1970) àti Jakendoff (1977) síde rẹ̀ ni ó ti pẹ̀ka tó sì gbọrẹ̀gẹ̀jigẹ̀ pẹ̀lú oríṣiríṣi àtúnṣe gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú iṣẹ́ Abney (1987) àti àwọn iṣẹ́ mìíràn bí i rẹ̀. Ìlànà pele mẹ́ta ni tíọ̀rì yìí gùn lé. Orí ni pele àkọ́kọ́. Orí yìí lè yọ sí pele àárín tí ó bá máa gba amúpé, èyí ni a mọ̀ sí pele Ìyọ-agbede méjì (Intermediate Projection). Pele kan tó kù ni ti Ìyọ-Àpólà (Phrasal tàbí Maximal Projection). Ó máa ń pọn dandan kí orí yọ dé pele àpólà ní pàtàkì tí irú àpólà bẹ́ẹ̀ bá máa ní Asọdọ̀tọ̀ (Specifier). Orí yìí ni a mọ̀ sí "X", ó sì lè dúró fún ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ̀rí wúnrẹ̀n aṣegírámà (Robberts 1997). Kìkì òté tó wà níbẹ̀ nipé ohun tí "X" bá dúró fún ni ó gbọ́dọ̀ yọ dé Àpólà tí yóò sì fun àpólà náà ní orúkọ.

(16) XP = Pele Ìyọ-àpólà (APX)

X' = Pele Ìyọ-agbede méjì

X = Pele Orí

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, ó ṣeé ṣe kí orí ní amúpé àti asọdọ̀tọ̀ gẹ́gẹ́ bí i ti ìhun tí a fẹ́ ṣe àlàyé rẹ̀. Bí ọ̀rọ̀ bá rí bẹ́ẹ̀, àtúnṣe gbọ́dọ̀ dé bá (16) gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn ní (17).

(17)




Pẹ̀lú ohun tí a ti fi hàn lókè, ó dájú pé àárín àpólà ọ̀rọ̀-orúkọ méjì tí wọ́n jẹ́ ìbátan ara wọn ni Fáwẹ̀lì Olóhùn àárin (**FOA**) àti **ti** máa wà. Mo ka àwọn méjèèjì sí orí-oníbejì tí wọ́n jẹ́ atọ́ka-ìní; ìyẹn, wúnrẹ̀n tó ń fi ìbátan hàn láàárín àpólà orúkọ méjì. Kìkì ìgbà tí a bá fẹ́ẹ́ ṣe ìtẹnumọ́ àti ìfún-àpólà olóhun ní Kéèsì ìní ni wọ́n jùmọ̀ máa ń jẹ yọ. Àpólà orúkọ àkọ́kọ́ máa jẹ́ ti ohun tí a ni, tí àpóla orúkọ kejì máa jẹ́ ti olóhun. Ìhun ohun tí a ń sọ̀rọ̀ bá ló wà ní (18).

(18)




[6] APIT dúró fún Àpólà oníbàtán. IT ni ó dúró fún wúnrẹ̀n ìní tí ó jẹ́ orí fún APIT.

Ó ṣeé ṣe kí **FOA** dá wà gẹ́gẹ́ bí atọ́ka ìbátan tàbí kí òun àti **ti** jìjọ ṣe àfihàn ìbátan yìí. Ìgbà mìíràn wà, ẹ̀wẹ̀, tí èyíkéyìí wọn kò níí jẹyọ. Ẹ wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

(19) a. ìwé **e** Túndé
b. ìwé **e ti** Túndé
d. ọmọ (ọn) **ti** Túndé
e. ìwé Ø Òjó

Àlàyé ti wà lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn àpẹẹre (19)[7] ṣùgbọ́n ó yẹ kí a sọ nípa (19b) àti (19e) ní ṣókí fún àǹfàní àwọn tí kò tíì ka irú iṣẹ́ tí àlàyé lórí wọn ti wáyé. Ohun tí Ajíbóyè (2005) dá lábàá ni pé **FOA** àti **ti** ló jùmọ̀ ń fún àpólà orúkọ olóhun ní Kéèsì ìbátan. Àbá yìí dá lé irú atọ́ka oníbejì yìí tí a ṣe alábàápàdé nínú èdè Korean (Schütze 1996 àti 2001).[8] Ní ti (18e), èrò Awobuluyi ni pé àìjẹyọ **FOA** níbẹ̀ jẹ́ ẹ̀rí pàtàkì tó fi hàn pé kì í ṣe iṣẹ́ atọ́ka ìbátan ni **FOA** ń ṣe bí kò ṣe fáwẹ̀lì àfibọ tó ń ṣe iṣẹ́ ìwòsàn fún ọ̀rọ̀-orúkọ tí fáwẹ̀lì ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀ ti pòórà. Ṣùgbọ́n lóju ti aṣèwádìí yìí, àìjẹyọ **FOA** kì í ṣe nítorí pé àpólà-orúkọ bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú fáwẹ̀lì. Àìjẹyọ yìí ni a gbà pé ó rọ̀ mọ́ òfin fonọ́lọ́jì tí kò fàyè gba ìjẹyọ fáwẹ̀lì mẹ́tà ní sísẹ̀ntẹ̀lé ní ààlà mọ́fíìmù tàbí ọ̀rọ̀. Òfin yìí ni kì í jẹ́ ká máa pe **FOA** níbi tí àpólà orúkọ bá bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú fáwẹ̀lì.[9] Ohun tí a dábàá ní ìlànà tíọ̀rì Onípele (X-bar) gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn

---

[7] Wo (Ajiboye 2005; 2007a,b; 2008).
[8] Níwọ̀n ìgbà tí iṣẹ́ yìí kì í ti í ṣe àfiwé pẹ̀lú èdè mìíràn, a rọ òǹkàwé láti wo Ajíbóyè (2005: 110, example 88) fún àlàyé àti àpẹẹrẹ láti inú èdè Korean.
[9] Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé, wo Ajiboye (2005, 2008).

nínú Abney (1987) ló mú kí ó ṣeé ṣe kí wúnrẹ̀n aṣegírámà náà jẹ́ orí, orí yìí ló sí fún àpólà náà ní ìyọsókè àtì orúkọ rẹ̀. Ìdí nìyí tí atọ́ka ìbátan (IT) tí ó jẹ́ orí náà ni ó yọ di Àpólà oníbàátan (APIT).

## Ìgúnlẹ̀

Èrò méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tó wà lórí wụ́nrẹ̀n ***ti*** inú Àpólà orúkọ ìní ni a ti gbé yẹ̀wò. A fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àràbọnilọ́rùn ni kí a sọ pé wúnrẹ̀n **ti** jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò-orúkọ nítorí kò ní ìrísí tàbí ìfọ́nká ọ̀rọ̀-orúkọ, bẹ́ẹ̀ ni kò lè ṣe iṣẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ rárá; kì í sì í ṣe ẹ̀yán ni ọ̀rọ̀ tó ń tẹ̀le bí kò ṣe àpóla-orúkọ olóhun. Ohun tí wúnrẹ̀n **ti** náà dúró fún ni orí nínú Àpólà oníbàátan, i.n.p., atọ́ka ìní ni **ti** ń ṣe.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Abney, Stephen Paul. (1987). The English Noun Phrase in Its Sentential Aspect. Doctoral dissertation. MIT.

Ajíbóyè, Ọládiípọ̀. (2005). 'Topics on Yorùbá Nominal Expressions'. Doctoral Dissertation. University of British Columbia, Vancouver, Canada.

Adeniyi Sunday. (1975). *Mo ti mọ̀*. LP Records.

Ajíbóyè, Ọládiípọ̀. (2007a). On the status of the Mid toned *ti* in Yorùbá Nominal Genitives. In Ozo-mekuri Ndimele (ed.). *Convergence: English & Nigerian Languages. A Festschrift for Munzal A. Jibril.* 943-956.

Ajíbóyè, Ọládiípọ̀ (2007b). High toned and Mid Toned Elements in Yorùbá. *Studies in African Linguistics.* Vol. 36.2 2007: 1-24.

Ajíbóyè, Ọládiípọ̀ (2008). 'Iṣẹ́ Fáwẹ́lì Olóhùn Àárín inú Àpólà Oníbàátan Yorùbá: Ẹ̀rí láti inú àwọn èdè mìíràn'. *Yorùbá: Journal of the Yorùbá Studies Association of Nigeria*. Volume 5(1):1-24.

Ajíbóyè, Ọládiípọ̀ (2011). 'Iṣẹ́ Fáwẹ́lì Olóhùn Àárín inú Àpólà Oníbàátan Yorùbá: Ẹ̀rí láti inú àwọn èdè mìíràn: A reply to Awobuluyi's rejoinder'. *Yorùbá: Journal of the Yorùbá Studies Association of Nigeria*. 55-82.

Awobuluyi, Oladele (2004). 'On the so-called Genitive Morpheme in Standard Yorùbá', read at the 24th WACL, University of Ibadan, Nigeria. August 1-6.

Awobuluyi, Oladele (2008). *Ẹ̀kọ́-ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀ L'édè Yorùbá*. Àkúrẹ́: Montem Paperbacks.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*. Òṣogbo: ATMAN Limited.

Baker, C. L. (1978). *Introduction to generative transformational syntax.* Prentice-Hall.

Bámgbóṣé, Ayọ̀ (1966). *A Grammar of Yoruba.* Cambridge University Press.

Bámgbóṣé, Ayọ̀ (1967). *A Short Yoruba Grammar*. Ibadan, London: Heinemann Educational Book Limited.

Bámgbóṣé, Ayọ̀ (1990). *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan: University Press Plc.

Chomsky, Noam (1970). 'Remarks on nominalization'. In R. Jacobs and P.S. Rosenbaum (eds.). *Reading in English Transformational Grammar.* Ginn and Co. Waltham. M.S. 184-221.

Jakendoff, R. S. (1977(. *X-Syntax: A Study of Phrase Structure*. Cambridge, M.A.: MIT Press.

Owolabi, Kola (1976). 'Noun-Noun Construction in Yoruba: A Syntactic and Semantic Analysis'. Unpublished Doctoral Thesis, University of Ibadan.

Robberts, Ian (1997). Comparative Syntax. Massachusetts: MIT Press.

Schütze, C. (1996). Korean 'case stacking' isn't a unifying use of case particles. In *Proceedings of the North East Linguistic Society* 26, K. Kusumoto (ed). 351-365. Amherst: GLSA Publications.

Schütze, C. (2001). On Korean 'case stacking': the varied functions of the particles *ka* and *lul*. *The Linguistic Review* 18: 193-232.